# APC INTERNET RIGHTS CHARTER IN YORUBA

# AKOSILE TEGBE FUN ILOSIWAJU IBANISORO LORI AWON ETO OMONIYAN TI ERO AYELUJARA

## ERO AYELUJARA FUN IDAJO ODODO AWUJO ATI IDAGBASOKE TO FESE RINLE.

Ero ayelujara je gbagede agbaye to gbodo si sile fun terutomo, ta a le lo ati eyi to wa laroowoto gbogbo eniyan. Bi ogunloko eniyan ti n ni anfaani si gbagede yii to, oke aimoye eniyan ni anfaani yii tun fo ru. Gege bi ilana ero ayelujara tagbaye eyi to wonu ara won timotimo bi egungun wonu eran, itankale anfaani nini ero ayelujara n waye pelu awon ayorisi ti ko dogba ati aigunrege eto amuluudun ati oro-aje lopo igba. Sugbon sibe, ero ayelujara ati awon oro ilaniloye miiran ati awon imo ero ibanisoro (ICTs) le je ohun elo alagbara fun itaniji araalu ati idagbasoke, lilodi si idajo aisododo ati sisoro iyato ati atinuda jade.

Egbe fun ilosiwaju ibanisoro (APC) gbagbo ninu ipa lati se kokaari ilaniloye ati ibanisoro laisi idiwo nipa lilo ero ayelujara eyi to se pataki si amuse awon eto omo eniyan gege bi a ti se la a kale ninu Akosile Eto Omoniyan Lagbaaye (todun 1948), Majemu Agbaye Lori Oro-aje, Eto Ajemawujo ati awon Eto Asa (todun 1976), Majemu Agbaye Lori Oro Ilu ati awon Eto Iselu (todun 1976) ati Ajo fun Imukuro Orisiirisii Ideyesi Awon Obinrin (todun 1980).

Ero ayelujara le je ohun elo lati wo awon eniyan agbaye ni agbara ti awon eto wonyi ba je kikiyesi, didaabo bo ati bibowofun.

Koko-oro 1: Ki ero ayelujara je kariaye

Koko-oro 2: Ominira siso tinu eni jade ati ibakegbepo

Koko-oro 3: Anfaani si imo

Koko-oro 4: Eko pinpin ati iseda ominira ati isisile orisun ati idagbasoke imo ero

Koko-oro 5: Tara-eni, sisolowolese, koodu idakonko

Koko-oro 6: Isakoso ero ayelujara naa

Koko-oro 7: Itaniji, aabo ati mimo awon eto

### **Koko-oro 1:** KI ERO AYELUJARA JE KARIAYE

Atiku 26, Kike-gbajare Awon Eto Omoniyan Lagbaaye (UDHR): Eto eko yoo wa fun ilepa idagbasoke lekunrere fun jije omo eniyan ati fun sise igbelaruge owo fun awon eto omoniyan pelu ominira pataki.

### **Koko-oro 2:** OMINIRA LATI SO TINU ENI JADE ATI IKORAJOPO

Atiku 18, UDHR: Olukuluku eniyan lo ni eto si ero okan, eri okan ati esin.

Atiku 19, UDHR: Olukuluku eniyan lo ni eto si ominira ero ati siso tinu eni jade, eto yii ro mo ominira lati mu ero eni duro laisi idena ati lati wari, lati gba, ati lati bu omi imo fun ni

mu ati awon oye nipa eyikeyii ile-ise ibanisoro laika awon aala si.

Atiku 20, UDHR: Enikookan loni eto si ominira apejo alaafia ati ikorajopo.

**Koko-oro 3**: NINI ANFAANI SI IMO.

Atiku 27, UDHR: Enikookan lo ni eto lati kopa ninu asa agbegbe (kan), lati gbadun awon ise ona, ati lati pin ninu idagbasoke imo sayensi ati awon ere to sodo sibe.

**Koko-oro 4:** PINPIN EKO ATI ISEDA OMINIRA ATI ISISILE ORISUN ERO AYARA-BI-ASA ATI IDAGBASOKE IMO ERO.

Atiku 27, UDHR: Enikookan lo ni eto lati kopa ninu asa igbesi aye awujo lati gbadun ise ona ati lati pin ninu idagbasoke sayensi ati awon ere to sodo sinu re.

**Koko-oro 5:** TARA-ENI, ISONILOWOLESE ATI KOODU IDAKONKO.

Atiku 12, UDHR: Ko si eni ti o gbodo dojuko sise atojubo si idakonko tara re, ebi re, ile tabi akosile re tabi lati tapo si aso aala eni.

**Koko-oro 6:** ISAKOSO ERO AYELUJARA:

Eto si alajose tiwa-n-tiwa to je isakoso ero ayelujara: Isakoso ero ayelujara gbodo je alajose ati tiwa-n-tiwa pelu kikopa awon ijoba, eka aladaani, ajo taraalu ati awon ajo ti agbaye. Ko gbodo si ijoba kan soso ti yoo ko ipa to ga ju tara yoku lo nipa ero ayelujara agbaye.

**Koko-oro 7:** ITANIJI, IDAABOBO ATI IMUSE AWON ETO.

Eto si awon eto idaabobo, itaniji ati eto eko: Awon eto omoniyan gege bi awon to n lo ero ayelujara gbodo je dida aabobo latowo awon Akosile ajo Agbaye fetoo omoniyan, ofin ati amulo ilana. Awon ajo alakooso ni ti orile-ede, ipinle ati agbaye gbodo je ki (oro) ilaniloye nipa awon eto ati ilana to ro mo ero ayelujara wa ni arowoto lofee. Eyi lo mo lila araalu loye lati fun awon eniyan ni imo lori awon eto won nigba ti won ba n lo ero ayelujara ati awon ona lati wa ojutuu si tite eto eni loju.

**Nipa Akosile naa**

Akosile yii koko waye laarin odun 2001 si odun 2002 latowo awon omo egbe fun ilosiwaju ibanisoro (APC) ati awon ajo alabaasisepo idanilekoo lori “Eto Ero Ayelujara” ni ile Europe, Asia, Latin America ati ile Afrika. Awon koko-oro ati ilana ti won gbe kale yannana awon ero ati afojusun lori awon eto omoniyan ati awon lajolajo lati lo ero ayelujara lofee, paapaa julo lenu ise won fun awujo, oro-aje ati idajo ododo lesekuuku. A n toka si ero ayelujara nipato;sugbon sibe gbogbo ilana wonyi se koko fun gbogbo ICTs (titi to fi kan ero ibanisoro, redio, ati awon yooku).

Akosile naa ko kun tan (kii se gbe-e-tan). O se agbejade die lara awon oro pato je pe olukuluku eniyan, awon egbe araalu ti kii se tijoba, ajo oniroyin, oluseto ati akojaanu, nilo lati sagbeyewo ninu awon igbiyanju won lati daabo bo eto atisoro gaaraga nipase ero

ayelujara ki won si mo agbara re lati seda aye to ni imo ilaniloye to ye kooro ati to kun fun ododo.

Akosile naa je jade ni ibere pepe, o si ni asomo pelu “Akosile Ibanisoro Eniyan” ati ti afo ti “Egbe Agbaye fun ohun Awon Eniyan ninu iroyin ati ibanisoro ni sentiuri kokanlelogun (21st Century).

Eda atunyewo Akosile yii nii lero ni pato lati ko mora awon oro to je mo akoso ero ayelujara to suyo ninu ipade Apapo Orile-ede Agbaye lori Egbe Oniroyin (WSIS) eyi to tun fara han ninu iroyin Igbimo Amusese lori Isakoso Ero Ayelujara ati Ipade Tunis fun Egbe Oniroyin. Bakan naa lo tun se agbeyewo apero lori ero ayelujara gege bi ohun rere taraalu lagbaaye to waye ninu awon apero ti Apapo Orile-Ede Agbaye lori Egbe Oniroyin (WSIS) ati ti Igbimo Amusese UNICT. Ipade atunyewo naa tun toka si awon aba Egbe fun Ilosiwaju Ibanisoro (APC) si Ipade Apapo Orile-ede Agbaye lori Egbe Oniroyin (WSIS) lori isakoso ero ayelujara.

Tite jade latowo Egbe fun Ilosiwaju Ibanisoro (APC), osu Belu, odun 2006.

1. Ogbeni Sunday Oyeniran Ilori, Alakoso eto ati isuna, Fantsuam Foundation, Kafanchan, Kaduna state, Nigeria, +2348036073597.